OWE
Bi a ba ran'ni ni işe
ẹru, afi t'ọmọ jẹ ẹ

# Irohin Yoruba

VOL X No 467 MONDAY JUNE 21, 1954 KOBO KAN (1d)

E ma a polowo oja
nyin sinu iwe
Irohin Yoruba

## Ajele Se Ase Apeje F'Oba Alake



ABEOKUTA- Fun ajọyọ ti oye "K. B. E." ti Ọba Oyinbo fi da Ọba Alake Abẹokuta Alaiyeluwa Ademọla Keji lọla, Ajẹlẹ Agba Abẹokuta Ọgbẹni I. F. W. Schofield pe awọn enia pataki fun ase apejẹ pataki si ile rẹ l'oke Igbein, Abẹokuta nitori oye ti Alake gba na, ati nitori ti Ọgbẹni J. M. M. Ọṣimosu "Provincial Education Officer, Abẹokuta, ti Ọba-birin Ilu Oyinbo na tun fi oye "M. B. E." da lọla pẹlu.

AWORAN oke yi ni ti Ọgbẹni Schofield Ajẹlẹ Agba Abẹokuta, ti o ngba ọwọ lọwọ Ọba Alake Abẹokuta nigbati Ọba Alake de fun Ipade Asẹyẹ ti Ajẹlẹ Agba na ṣe fun u lati ba a fi yọ ayọ Oye K.B.E. ti Ọba-birin ilu Oyinbo fi da Ọba Alake na l'ọla.

## S. L. Akintola Fo Lo Ilu Oba



Ni ọjọ kẹtadinlogun oṣu yi ni Oloye S. L. Akintola Gbakeji Olori Egbe Action Group ba ọkọ ofurufo lọ lọ si ilu Oyinbo lati lọ ba Iyawo rẹ lọhun ti o ti siwaju rẹ lọ fun ọsẹ meji sẹhin. Nwọn lọ fun isinmi lati gba atẹgun fun igba diẹ awọn a si pada ni ipari oṣu ti mbọ yi. Oloye Akintola na ni o nlagbere ninu aworan oke yi lati inu ọkọ-ofurufu fun awọn ero ti o sin in wa sibẹ ni Ikeja.

## Oba Ademola Ko Egba L'enu Jo

OBA Alaiyeluwa Ademọla Keji K. B. E. Alake Abẹokuta, pe ọpọlọpọ enia fun ase apejẹ, ni Afin rẹ (Afin Alake) fun idunnu oye "K.B.E." ti Alaiyeluwa Elizabeth Keji (Ọba-birin Ilu Oyinbo) fi da a (Alake) lọla nigbati Ọba-birin na nṣe ajọyọ ọjọbi rẹ ti ọdun ni, ti o ṣe ni ọjọ kẹwa oṣu yi.

A ko tun ṣeṣẹ le ma sọ bi ase apejẹ na ti larinrin to, "Ngbọ! Hihan ẹpo abi airowo ra a, Ọba pe'lu o o jo ni ọjọ wo ni wa lo r'owo pe tirẹ ?" Awọn Ọlọpa Onilu Ijọba Ẹgba [N. A. Police Band] ni nwọn wa ṣere fun wọn nibẹ.

Diẹ ti ninu awọn ti o wa sibẹ ni Ajẹlẹ agba Abẹokuta Ọgbẹni I.F.W. Schofield ati Iyawo rẹ Alaiyeluwa Ọlagbegi Keji, Ọlọwọ Ọwọ, Ọba Osilẹ Oke Ọna, Ọba Agura Gbagura, Ọba Olowu Owu, Olubata Ibara, Adiọ-Agba Ọgbẹni Adetokunbọ Ademọla, Ọlọla Iyaafin Rẹmi Aiyedun M.H.A., Oloye Akinwande Thomas Oluwo Iporo, Oloye E.O. Ọdẹtola Lisa Itoku, J.O. Kashimawo Lẹmọ Ilewo, Oloye Adefolu ati Dọkita Adefolu pẹlu ọpọlọpọ awọn Oloye ati Ọlọla ti ko si aye lati daruko wọn.

Ade a pẹ lori Bata a pẹ lẹsẹ Ọba o, Ademọla Keji ọmọ Erin-jogun ọla, Kabiyesi !

## Ogun Lo Si Ilu Oyinbo



Ọgbẹni M. A. Ogun ati Ọgbẹni M. A. Ajasin lọ si ilu Oyinbo, awọn mejeji jẹ ọkan ninu Igbimọ "Western Regional Production Development Board." Fun iṣẹ Igbimọ yi na ni nwọn ba lọ si ilu Oyinbo fun.

## Oloye Rotimi Williams Gb'Eye

EKO- Ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kejila oṣu yi ni awọn Ẹgbẹ Area Council ṣe ẹyẹ alarinrin kan fun Oloye Rotimi Williams ti iṣe Alaga Igbimọ Munisipa Eko ni Gbọngan Apejọ Glover Memorial fun ti ilu Oyinbo ti o ti lọ ti o si pada de laipẹ yi ati fun iṣẹ ti o ṣe lọhun. Oloye Baba Eko, Dọkita Akinọla Maja ni o ṣe Alaga, awọn ti o joko niwaju pẹlu Alaga na ati Oloye Rotimi Williams ni Alaiyeluwa Adele Keji, Ọba Eko ti iṣe Alakoso Igbimọ Munisipa Eko ati awọn Ijoye Eko ati Iyaafin Maja ati Alaiyeluwa Ọdẹmọ Ishara ati Eni owọ ninu Archbishop Taylor C. B. E., Ọlọla Koto Abayọmi ati Iyawo rẹ ti o ṣe Alaga fun awọn Ẹgbẹ ti o nṣe ẹyẹ ọjọ na, ati Iyaafin Williams.

Ọlọla Iyaafin Abiyọmi ni o fi ẹbun ati iwe apọnle ti awọn Ẹgbẹ na ko fun Oloye na.

Alufa (Canon) Dedekẹ ni o fi adura si ipade ẹyẹ na, Ọgbẹni A. O. Lawson ni o fi Alaga ọjọ na han pẹlu ọrọ apọnle.

...na ti o sọ ọrọ apọnle ... pupọ nipa awọn aye ... ti Oloye Rotimi Williams na wa ati pe bi o ti ... ọmọ kekere ti nhuwa ... to.

Nigbati Oloye ... Williams na dide ... pẹ lọwọ awọn Ẹgbẹ ... ṣe ẹyẹ na fun un ati fun ẹbun ati iwe apọnle ti awọn fun un, gbogbo awọn enia ti awọn ne si ibẹ bẹrẹ si ... rẹ pẹlu atẹwọ, o si dupẹ lọwọ wọn pupọ.

Ẹyẹ ọjọ na dun o larinrin, ọpọlọpọ onjẹ adidun ni nwọn fi le ebọ gbọ awọn alabaiyẹ ọjọ na lọrun, awọn Ọlọpa onilẹte Ijọba ni o wa lu ilu fun wọn nibẹ ni ọjọ na. Irohin ko to amọ̀... ... ẹyẹ na dun, o ga lọ...

## Mexi Godo Tun Tu Ole Kan Fo

OGBENI MEXI ỌLA GODO, awakọmọtọ-ero (Taxi Driver) ti a sọ irohin rẹ ni igba kan pe, awọn enikan ni ki o ba awọn keru lọ si ile wọn ṣugbọn nigbati o fura pe ẹru ole ni nwọn sọ pe ki on ba wọn ko ni o ba wa mọto doriko ṣọbu awọn Ọlọpa, ti nwọn fi ba ole na ṣe ẹjọ ti nwọn si sọ fi s'ẹwọn, tun tu ole kan fo.

Laipẹ yi bi ero ti ndu-witiwiti lati wọ mọto ni Ọgbẹni kan James Onifade ba fi igba ta pe awọn yọ Kalamu "Fountain Pen" ti on fi ha apo aiya ... on lọ.

Ọgbẹni Mexi Ọla Godo (Tax Driver) ... ibẹ, ni o si duro ni ki nwọn ... so pe ... Kano ti o ... Lawson Street, Lagos 13, wọ, ki nwọn si tun ... inu agbọrun rẹ. Nwọn ... Hausa na lara wọ pẹlu ion, nwọn si ba "Kalamu" na ninu agbọrun rẹ. Iye owo Kalamu (Fountain Pen) na jẹ sile mejila-abọ (12/6).

Nigbati ọran na de iwaju adajọ ti adajọ na si ri ẹri ti o daju pe ni tọtọ ni Mallam Shehu Kano ji Kalamu na ni adajọ na ba sọ ọkunrin Hausa na si ẹwọn oṣu mejila oniṣẹ-aṣekara.

PR-GRESS

O! ARE U MISSING

16 hours of it for less than

3D A DAY---GET REDIFF-SION

